# IPÈ ABRAHAMU

### Gẹnẹsisi 11:31, 32; 12:1-9

### ẸKỌ 8 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Abrahamu gbà Ọlọrun gbọ́, a si kà a si ododo fun u" (Romu 4:3).**

**Oludasilẹ Orilẹ-ede Kan**

Ọlọrun ni eto kan lati ipilẹṣẹ ayé nipa eyi ti a le fi ra eniyan ti o ti ṣubu pada, ki a dari ẹṣẹ rẹ ji i, ki o ba le wà ni imurasilẹ lati lọ si Ọrun. Bi a ti n ka Iwe Mimọ Majẹmu Laelae a ri iṣipaya eto Ọlọrun lẹsẹẹsẹ -- diẹdiẹ, ṣugbọn ni ṣisẹ n tẹle pipé. Ẹsin mimọ́ ni o ṣe pataki ju lọ ni igbesi-ayé eniyan, Ọlọrun si ti ṣe eto ki awọn eniyan le ni anfaani a ti kọ́ ọna ti o tọ́ lati fi sin In.

Ọlọrun n fẹ orilẹ-ede ti Oun le pe ni ti Rẹ̀, ti yoo waasu Ihinrere Rẹ̀ fun awọn araye ti o kù. Lati inu orilẹ-ede naa ni Jesu, Olurapada, yoo ti dé, nipasẹ Ẹni ti gbogbo eniyan yoo ti di ẹni ibukun. Ọlọrun kò fi agbara mu awọn eniyan kan lati jẹ orilẹ-ede ti Rẹ̀, ṣugbọn O fi ẹni kan ati ẹbi rẹ̀ bẹrẹ. Ọkunrin yii ni Abramu, ẹni ti a tun wa pe ni Abrahamu, ẹni ti o gbé ni Uri ti Kaldea, laaarin awọn eniyan ti n bọ oriṣa. Ọlọrun pe Abrahamu jade kuro laaarin gbogbo awọn eniyan wọnyii lati di baba awọn ayanfẹ Rẹ̀. Nigba mẹrin ọtọọtọ ni Ọlọrun fun un ni ileri pe Oun yoo sọ ọ di orilẹ-ede nla (Gẹnẹsisi 12:2; 17:6; 28:3; 35:11).

**Baba Rere**

Ọlọrun le ri ero ati ifẹ ọkàn Abrahamu. O mọ pe Abrahamu yoo fi otitọ sin Oun, yoo si jẹ baba rere fun awọn eniyan Rẹ̀. O wi pe Abrahamu yoo saa di orilẹ-ede nla ati alagbara, ati gbogbo orilẹ-ede ayé ni a o bukun fun nipasẹ rẹ̀, "nitoriti mo mọ̀ ọ pe, on o fi aṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ ati fun awọn ara ile rẹ̀ lẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o ma pa ọ̀na OLUWA mọ́ lati ṣe ododo ati idajọ; ki OLUWA ki o le mu ohun ti o ti sọ fun Abrahamu wá fun u" (Gẹnẹsisi 18:18, 19). Ọlọrun ṣe ileri pe iru ọmọ rẹ̀ yoo jẹ ainiye, bi iyanrin òkun; ati bi irawọ oju-ọrun. Awọn wọnyii ni awọn Ju, ati pẹlu awa ti a gba Jesu gbọ́ ti a si ni igbala ni tootọ: "Bi ẹnyin ba si jẹ ti Kristi, njẹ ẹnyin ni irú-ọmọ Abrahamu, ati arole gẹgẹ bi ileri" (Galatia 3:29).

Ọlọrun ṣeleri fun Abrahamu pẹlu pe Oun yoo fun un ni gbogbo ilẹ Palẹstini: "Irú-ọmọ rẹ li emi o fi ilẹ yi fun." Ni akoko miiran Ọlọrun wi pe: "Gbogbo ilẹ ti o ri ni, iwọ li emi o sa fi fun ati fun irú-ọmọ rẹ lailai" (Gẹnẹsisi 13:15). Ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu duro titi laelae. Abrahamu ko si laye lati ri i ki awọn ọmọ rẹ̀ ni ilẹ naa, ṣugbọn "nipa igbagbọ́ li o ṣe atipo ni ilẹ ileri, bi ẹnipe ni ilẹ àjeji, o ngbé inu agọ́, pẹlu Isaaki ati Jakọbu, awọn ajogún ileri kanna pẹlu rẹ̀: nitoriti o nreti ilu ti o ni ipilẹ̀; eyiti Ọlọrun tẹ̀do ti o si kọ́" (Heberu 11:9, 10). Ọkàn Abrahamu n wo ohun ti Ọrun; ọrọ̀ ti o ni ni ti ẹran-ọsin ati wura, tabi ifẹ ere aye yii, ko fi igba kan fa ọkàn rẹ̀ kuro lọdọ Ọlọrun ati awọn ileri ti o ti fi fun un.

Isaaki ni ọmọkunrin Abrahamu; Jakọbu jẹ ọmọ-ọmọ Abrahamu, Jakọbu si ni baba awọn ọmọkunrin mejila ti o wá di olori awọn ẹya Israẹli mejila ti i ṣe orilẹ-ede Ju. Awọn wọnyii jẹ ayanfẹ eniyan Ọlọrun, O si fẹran orilẹ-ede naa. Nigba ti wọn ba ṣẹ̀ si I, ti wọn si tọ ọlọrun miiran lọ, ti wọn si sin oriṣa, Oun a pè wọn pada. Awọn ti o ba yi pada ni ironupiwada ni a mu bọ̀ sọdọ Ọlọrun. Ninu Deuteronomi 7:6 a ka a pe "OLUWA Ọlọrun rẹ ti yàn ọ lati jẹ́ enia ọ̀tọ̀ fun ara rẹ̀, jù gbogbo enia lọ ti mbẹ lori ilẹ."

Nipasẹ awọn Ju, ọpọ orilẹ-ede miiran ni o ti di ẹni ibukun. Ọlọrun ṣeleri pe: "Emi o bukun fun awọn ti nsúre fun ọ, ẹniti o nfi ọ ré li emi o si fi ré." Lati igba yii wá, awọn orilẹ-ede ti wọn ti fun awọn Ju ni ibugbe ti là. Bẹẹ gẹgẹ, awọn orilẹ-ede ti wọn ti ṣe inunibini si awọn Ju ti lọ silẹ ninu ijatilẹ. Ọrọ Ọlọrun jẹ́ otitọ, ohunkohun ti O ba si wi yoo sa ṣẹ dandan.

**Wọn N Gbé Inu Ilẹ Ti Wọn**

Lẹyin ti awọn Ju kọ Jesu ti wọn si kan An mọ agbelebu, a tu wọn kaakiri gbogbo agbaye. A ko i ti mu ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu ṣẹ pe wọn o ni gbogbo ilẹ Palẹstini, ṣugbọn o daju lonii pe yoo ṣẹ gẹgẹ bi o ti daju nigba ti a sọ ọ ni iwọn egbejidinlogun ọdun o din ọgọrun (3,500) sẹyin. Ọlọrun yoo ko Israẹli jọ, apa kan ti o ṣẹku ninu wọn yoo si maa gbé ni alaafia ni Ilẹ Mimọ́ naa: "Sa wò o, ọjọ mbọ̀, li OLUWA wi, ti nwọn ki yio tun wipe, OLUWA mbẹ, ti o mu awọn ọmọ Isaẹli jade kuro ni ilẹ Egipti: ṣugbọn pe, OLUWA mbẹ, ti o mu iru-ọmọ ile Israẹli wá, ti o si tọ́ wọn lati ilu ariwa wá, ati lati ilu wọnni nibi ti mo ti lé wọn si, nwọn o si gbe inu ilẹ wọn" (Jeremiah 23:7, 8). Eyi yoo ṣẹlẹ ni akoko ijọba Ẹgbẹrun-ọdun.

**Ayọ̀ Abrahamu**

Bi o tilẹ jẹ pe Abrahamu ko ni ayọ̀ riri imuṣẹ awọn asọtẹlẹ wọnni nigba ti o wà ni ayé, inu rẹ̀ dun ni igbagbọ́ pe Ọlọrun yoo ṣe ohun ti O ti leri. Jesu sọ, niwọn ẹẹdẹgbẹwa ọdun (1900) lẹyin akoko Abrahamu pe, "Abrahamu baba nyin yọ̀ lati ri ọjọ mi: o si ri i, o si yọ̀" (Johannu 8:56). Abrahamu mọ pe nipasẹ Jesu ni igbala yoo ti wá. "Ihinrere" naa ni igbala Oluwa Jesu Kristi. Paulu Apọsteli wi fun awọn Onigbagbọ Galatia pe: "Iwe-mimọ́ si ti ri i tẹlẹ pe, Ọlọrun yio dá awọn Keferi lare nipa igbagbọ́, o ti wasu ihinrere ṣaju fun Abrahamu, o nwipe, Ninu rẹ li a o bukún fun gbogbo orilẹ-ède" (Galatia 3:8).

Wo àyè nla ti Abrahamu ni lati di ninu eto ayeraye! Nitori o gbọran si Ọlọrun o ri igbala, nisisiyii gbogbo Onigbagbọ lonii ni n gbadun awọn ibukun ti ẹmi ti a ti ṣeleri fun iran Abrahamu.

**Ileri Fun Wa**

Iwọ le wi pe ko ni nira lati jade ni igbagbọ ati lati fi ile rẹ silẹ ki o si lọ si ilẹ ajeji bi Ọlọrun yoo ba fun ọ ni ileri ti o tobi to eyi ti o ṣe fun Abrahamu. Sa ronu ohun ti Ọlọrun ti ṣeleri fun wa: "Ẹ fi etí silẹ ẹnyin ará mi olufẹ, Ọlọrun kò ha ti yàn awọn talakà aiye yi ṣe ọlọrọ̀ ni igbagbọ́, ati ajogun ijọba na, ti o ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ?" (Jakọbu 2:5). "Ṣugbọn ẹniti o ba nwo inu ofin pipé, ofin omnira nì, ti o si duro ninu rẹ̀, ti on kò jẹ olugbọ́ ti ngbagbé, bikoṣe oluṣe iṣẹ, oluwarẹ̀ yio jẹ alabukun ninu iṣẹ rẹ̀" (Jakọbu 1:25). "Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède gbogbo, … ẹ si kiyesi i, emi wà pẹlu nyin nigbagbogbo, titi o fi de opin aiye" (Matteu 28:19, 20). Awọn ọmọlẹyin Jesu ni tootọ ni ibukun Rẹ̀ lori wọn nihin ninu ayé yii, wọn si ni ileri ipin ninu ijọba Jesu nigba ti O ba pada wá.

Ki i ṣe ọpọ eniyan ni o n fẹ lati gbọran patapata si Ọlọrun, ki wọn si jọwọ ifẹ wọn fun Un. Wọn n fẹ ibukun Rẹ̀, ipamọ Rẹ̀, agbara iwosan Rẹ̀; ṣugbọn wọn ko fẹ ṣe ifẹ Rẹ̀. A le diwọn igbesi-ayé wa wo nipa bibeere lọwọ ara wa pe: "Jesu yoo ha ṣe ohun ti mo n ṣe yii bi o ba wà ninu ayé? Jesu yoo ha lọ si ibi ti mo n lọ, bi Oun ba wa nihin?" Aṣoju Kristi ni a jẹ́ ninu ayé yii. A ha yẹ fun orukọ yii bi? Bi awa ba n wá lati wu Ọlọrun, àyà kò ni fò wá lati jade lori ileri Rẹ̀, gẹgẹ bi Abrahamu ti ṣe.

Abrahamu ṣe ipa ti rẹ̀ ninu ilana nla Ọlọrun. Ọrọ naa sọ fun ni pe oun pẹlu awọn ẹbi rẹ jade lati lọ si Kenaani, "ni ilẹ Kenaani ni nwọn si wá si." Ọpọlọpọ ohun irẹwẹsi ni o wà lọna naa, ṣugbọn igbagbọ́ Abrahamu ko yẹ̀. A ba le fi igbesi-ayé wa le apẹẹrẹ baba igbagbọ, ki a si mu ifẹ Ọlọrun fun wa ṣẹ!

## AWỌN IBEERE

1 Nibo ni Abrahamu n gbé nigba ti Ọlọrun kọ́ pè é?

2 Ki ni awọn idile Abrahamu ti n sin tẹlẹ ri?

3 Ki ni Ọlọrun n fẹ lọwọ Abrahamu?

4 Darukọ diẹ ninu awọn ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu?

5 Nibo ni Ilẹ Ileri wà?

6 Ẹni nla wo ni a o bi sinu idile Abrahamu?

7 Bawo ni a ṣe le di ọmọ Abrahamu?